
LILO ABELA PELU PSALM FUN AKUNSE ISE AGBARA PELU ALA(DREAM)

IN CONJUCTION WITH

ORI OKE ASE GBOGUNMI

LATI OWO OLUDASILE LILO ABELA ATI PSALM WOLI OLUWASEUN , BABA ASE ORO.



AGBALUKU,
ARIGIDI-AKOKO,
ONDO STATE/
KOGI STATE.

TELEPHONE NUMBER:

07025859828



WOLI JOSEPH FEYISAYO
MAMA ASE ORO
07033588101

ORO IYANJU DIE

Mo se iwe yi fun anfani gbogbo eniyan lokunrin lobirin, omode ati agba. Abela, Ororo olifi, turari ati psalm je ohun elo Pataki fun awon onigbagbo, gegebi oluwa ti fi le awon osise olorun igbani lowo num 8:4, lef 24:2-4 ati bebeelo.

Nitori na o ye ki a mo dajudaju pe abela je nkan Pataki ti o nsise pelu ireowo, aseyori ati ohun gbogbo daradara miran pelu.

ORISIRISI AWON ABELA ATI ISE WON

A ti mo tele gegebi imo olorun pe olukuluku eda lo n fe agbara ati se rere laye. Awon awo wonyi je agbara ati ohun Pataki fun iranlowo awa eda. Awon awo nan i wonyi ati ohun ti a nlo won fun:

Awo funfun wa fun iyasi mimo
Awo pupa wa fun iferan
Awo pink wa fun aseyori
Awo pupa wa fun iferan
Awo ofefe wa fun Agbara Emi
Awo Orombo wa fun Iwa Oju rere
Awo dudu wa fun Isegun Esu
Awo Bulu wa fun Alaafia ati ire owo
Awo brown wa fun Ayo ati idunu
Awo purple wa fun Agbara Olorun
Awo gold wa fun Orire

E jowo farabale ba awon eto adura lo pelu abela ti ayan fun ohunkohun ti onse edun okan re ki ato bere sini ise adura naa.

AGBARA ABELA PELU ADURA NINU OLORUN.

Tan abela merin ki o si joko larin re pelu edun okan re. Gbadura si olorun ki o si ka adura oluwa. Agbara olorun yio siji bo o. imole olorun yoo tan yi o kan, gbogbo eniyan yoo si ri ogo olorun lara re, yoo si ni ife si o, ona re yoo yori si rere.

Awon adura abela wonyi ni a se eto won gegebi awon alaye merin ile orun afefe, ina gegebi agbara awon alaye ayanmo tire lati odo eleda gbogbo eniyan.

Akiyesi:

1) O ye ki a ya yara kan soto larin ibugbe wa fun akanse adura nibiti kosi ariwo ati iyo lenu ati tabili kan ki ate aso funfun sori re, eyi yoo je ibikan Pataki
2) O ye ki a ma lo turari ati ororo olifi pelu awon ate abela wonyi. A o ma fi oro olifi yen pa abela lara ki a to tan **.**
3) Ani lati wa ranti awon iye ojo ti ako si eto pe a ni lati se adura na gba ki a to pari re.
4) Ani lati tan obela funfun meta. Ekini ni oruko Olorun Baba, Ekeji ni oruko olorun omo, ati eketa ni oruko olorun Emimimo leyin naa a o wa tan awo eyiti Adaniyan fuu ohun tin se edun oka, wa si eyiti o wa ni arin meji eyiti nse ti olorun omo.

APEJUWE RE NIYI

Abela funfun	Abela Funfun	Abela Funfun
Okan ti baba	Okan ti omo	Okan ti Emi-mimo

Awon abela fun edun okan re Nigbati a o ke aba ti tanbagi tan fi ororo olifi pa lara a o tan ina si funfun meta leyin na a o tan awo ti a o fi se adura na.

ONA MIRAN PATAKI TI O LAGBARA JULO LATI MALO AKOPO ORISIRISI AWO ABELA FUN ONIRURU ADURA.

Wonyi ni ona ti a ngba tan abela larin ose fun adura, pelu iwe ti a o ma ka fun ojo kookan. Johanu ori1ati 5,fun ojo kookan

Sunday tan abela alawo ofefe {yellow}

Monday	funfun{white}
Tuesday	pupa{red}
Wednesday	popilu {purple}
Thursday	bulu {blue}
Friday	Eweko {green}
Saturday	dudu {black}

LILO EYO ABELA KAN FUN AKANSE ADURA: ABELA FUNFUN

A maa nlo fun iranti oku ati lati pe Agbara Emimimo sokale, a o malo abela funfun kan ni ojo Monday,Wednesday,Friday, a o ma fi ororo olifi

paa lara ati lilo turari, a o ma ka Psalm 112, atun nlo fun gbara adura gbigbona ni ojo meta wonyi nipa kika Isaiah 61, Psalm 112 ati113.

Red Candle

Fun iferan lati da olufe re to lo pada bo. Bi Iyawo re tabi ore ti o feran fi o sile lo, ojo mesan ni a o fi se eto adura yi, a o fi ororo olifi para abela pupa kan, a o sun turari, e o pe oruko olufe na nigba meta, ao ka psalm 125 lee meta ati adura atokanwa.

Pink Candle

Fun aseyori a nlo abela yi, fi gbadura ni ojojumo ninu ose titi a ofi ri pe nkan ti a n fe tewa lowo nigba miran a nlo leemeta lose. Nigbati a ba ti fi ororo olifi palara a o sun turari a o ka Psalm 98 lemeta pelu adura.

Yellow Candle

Awo yelo wa fun ki agbara emimimo le ma posi lara eniyan o si tun mu ki a ma rinran tabi laala ijinle, a o wa se adura yii ni ojo Tuesday, Thursday, Saturday. A o ma ka Psalm 59 leemeta, a o fi ororo olifi palara abela ao si ma lo turari pelu adura.

Orange Candle{orombo}

Awo Orangbo lati jeki wa ati ise wa maa wu eniyan gbogbo, a o ka Psalm 46 leemeje, nipa fifi ororo olifi palara eti lilo turari fun ojo mesan.

Black Candle {dudu}

Abela dudu lati tu awon ota ka ati lati le eniyan buburu ni ayika ile wa, maa lo abela yi ni ojo Aje, Ojoru, Eti titi gbogbo igbogun eniyan yoofi tan patapata. A oka Psalm wonyi 104,144,145 leemeta pelu fifi ororo olifi pa lara ati lilo turari.

Blue Candle {bulu}

Abela yi a ma mu ire owo wole kiakia ati lati so agbara eniyan di otun ninu Emi olorun. A o ma tan ni ojo Ojoru,Eti,Aiku. Ao fi ororo olifi pa ara abela na, a o si sun turasi , a oka Psalm 18 lemeje.

Brown Candle{burahu}

Abela awo brown yi, a ma nlo lati fi wa ohun ini wa ti o sonu, o si tun mu ki ibale okan fun olufe wa. Ojo mesan ni a o se adura yi. A o ma sun turari, a o gbadura tokantokan a o ka Psalm 71 ati 54 leemeta-meta.

Green Candle {awo eweko}

Abela yidera fun eni ti o n wa ise rere ati ilosiwaju ninu ise, a o fi ororo olifi palara a o sun turari. Ao ka Psalm 61[9times] ni ojo Monday, Tuesday ati li arin ose li ao ma ka titi di Saturday ojo abameta

PURPLE{POPILU}CANDLE

Abela yi ma n fun ni lagbara lati ko ara eni ni ijanu ati lati le fun wa ni agbara lati to awon to wa nitosi sona rere ati ona olorun. Ao ma lo won ni ojo Wednesday ati Friday. Ao ma ka Psalm 56[7times] lemeje.

Gold Candle {Golu}

Abela yi ma mu owo wole, o si ma nle agbana jina, ati lati fun nini emi agbara ti a o fi ma so mo na awon Psalm 2 eniyan wa sona rere. A o ma lo ni ojo Tuesday ati Sunday. A o w ka Psalm 150 (3times) pelu adura ati ororo olifi ati turari.

ETO FUN ISEGUN ONIRURU ISORO

Wa ninu awe fun ojo meje ni ojo kokan tan abela funfun meje Gbadura o se daudau ko je abela tuutuu lojojumo. Bi adura re ba se pe tolo ma fi ta bi abela re yoo se ni alo pe si. Ranti lati gbadura laro, losan ati lati mo fun wape ma gbadura lai simi 1thesalonnias 5vs17

TITAN ABELA LATI TU AWON OTA KA

Nigbati ota ba dide si eniyan ti o bafe da won ru, a o tan abela ofefe (yellow) kan, abela dudu meta, abela bulu meta

ASIRI LILO PSALM PELU ORUKO PELU ORUKO

1. FUN ABOYUN.PSALM 1

Bi obinrin ba ni oyun yio ma ka ese kini de iketa ni igba meta lojo yio si ma gbadura si sinu omi pelu pipe oruko mimo yii sin i eemeta: ELISADI tabi JEHOFA SALON

ADURA: Oba Olodumare Onise Iyanu, iwo ti o di eru fun aboyun mase lai jeki obinrin yi ki o bi tibitire ki o si fun ni omo Alafia ti yoo wulo fun-un ati oko re loruko mimo re ti a n pen i JEHOFA SALONI, ELISADI

Psalm 2. FUN ORI FIFO.

A o ka gbogbo psalm yi sinu omi pelu oruko Olorun yi: O SADI, JEHOFA MALI ni igba meta yio si fi omi na we ori.

Psalm 3. EHIN DIDUN ATI ORI FIFO.

O dara fun efori ati ehin didun a o ma ka Psalm yi ni emeta ki a si ma gbadura pelu oruko Olorun: ADONI TABI JEHOFA RHAF fun wiwe.

ADURA

Oluwa alanu Oluranlowo gbogbo eniyan ma sa lai se iwosan fun eniti ehin didun ati fun eniti ara nhun ki won le san ninu aisan wonyi. Pipe oruko Olorun leemeta.

Psalm 4. KI OLORUN LE JE AMONA ENI

Nigbati ko ba si oluranlowo a o ma ka psalm yin i igba meje ni kutukutu owuro lai soro seniyan pelu igbagbo. SELAH TABI JIHEJE.

Psalm 5. OJURERE LATI ODO GBOGBO ENIA

A o ka psalm yi sinu olive oil ni igba meta, a o fi we pelu oruko mimo yi SANANJA TABI JEHOFA

PSALM 6. OJU DIDUN

Fi psalm yi gbadura fun eniti oju ndun, a o fi ya omi si mimo fun mimu ati wiwe oju na pelu oruko Olorun yi: JEHOFA ELILA TABI JASIKABAAL HATGHINA

ADURA

Olorun iwo ti o da oju si agbari lati ma fi reran, jowo se iwosan fun oju yi ki o san

PSALM 7. IGBALA LOWO OTA

Ka ni arin oru nihoho pelu iresile okan gidigidi, Oluwa yoo segun fun o, ka nigba meje pe oruko mimo yii EL-EL-JONI tabi O ELI ELI JONI

ADURA

Olusegun, Ajasegun ode orun, odo re ni ohun gbogbo ti wa ma s alai segun fun mi. AMIN.

PSALM 8. IGBEGA NIBI ISE

Eniti o ba nfe igbega nibi ise yi o ka psalm yi pelu oruko Olorun yi RECH MIAL EEL Tabi JOFE (ITUMO eyi tin se Olorun Alagbara ati Olorun ti ogo re ga koja ipa gbogbo enia.

ADURA

Olufe irepo je ki nri ife aisetan lati odo arakunrin tabi arabinrin mi ati ni gbogbo ojo aye mi, ki oju rere re le ma ba mi lo ni o.

PSALM 9. BI OKO TABI AYA BA JE ALAILERA

FI Psalm yi gbadura fun eniti orisirisi aisan mba ja, ya omi si mimo, fun mimu ati wiwe pelu oruko Olorun yi EHIJI ESIKU EHIJI tabi ELOHIM

PSALM 10. WERE TABI IGBONA

BI ASE LE LO AWON ORO MIMO LATI FI BEERE NKAN LOWO OLORUN

ALETH 1	ZAN 24	CAPH 11	PE 23
BETH 10	CHETH 22	LAMED 9	PSADDI 21
SEMELI 8	TENT 20	MEM 7	KOPH 17
DALTH 6	JAJI 18	NUN 5	RASH 17
HE 4	HAI 16	SAMECH 3	SCHIN 15
VAU 2	JODI 14	AIN 12	TAU 13

1. ALETH: Bi odomode kunrin tabi odomode binrin ti ko tin i aya tabi oko ba fi owo kan eleyi ki a so fun pe igbesi aiye oko tabi aya na yio dara ati pe tio ba le fe eniti ngbero lokan nigbesi aiye won yio dara.

Bio ba je pe eniti o tin i iyawo nile lo ba fi owo kan eleyi ki a so fun pe iyawo re yi o bi omo pupo, ati pe onibere yin i lati pe laiye nitoripe emi gigun wa fun, ati pe ohun ti ko je ki okan re bale yio yori si rere.

2. VAU: Enikeni ti o ba mu eleyi ki a so fun pe ore re yi o dale re, bi o bas i nfe lati se kan ti o je mo ile ejo ko ni jare nibe. Bi o bas i je pe owo sise ni owo ti e ba mu lo sibe ko ni bawole ati papa ki eleyi sora ki aiye mase so di onigbese tabi ase danu.

3 SAMECH; Ori rere wa fun wa o,laipe iwo yio bere si lati ma rise ti yio si ya iwo papa lenu.Iwo yio ma ri ife awon enia nlanla tio ni ola ju o lo.Ati papa iwo yio ri iroyin rere kan gba laipe.

4 HE; Eleyi yio so owo tabi ohun lai kan nu laipe.Nitorina ko sara fun ohun ti o bere si ,Ere ko si nibe.

5 NUN; Enikeni ti o ba fi owo kan eleyi kio mase faya kadara lon da lamu kise aiye tabi amo ise se to egba se.Bi oba ti tubo tun iwa re se lodo

gbogbo enia ‘asiko ti ari re yio dara kop e mo ‘tubo mu suru fun ohun tio fe se.

6. DALTH: Kos i ona nibi ohun ti o fe se, fi sile ni asiko yin a tabi ko se omiran

7. MEM: Bi obinrin lo ba mu eleyi yio ni oko rere, bi okunrin lo ba si mu yio ni aya rere, ati papa ti o ba je pe eniti o tin i oko tabi okunrin ti o tin i aya, ki o mase ba oko tabi aya re ja. Nitoripe eleda awon mejeji feran ara won, atipe omo rere ni won yio bi. Eniti o ba mu eleyi ohunkohun ti o ba ngbero lokan lati se yio yori sir ere.

8. GAMELI; Ami Ohun rere ni eleyi, gbogbo ero okan eleyini yoo yori sir ere ati pe ohun rere ti ko tile ro tele nbo wa.

9. LAMED: Enikeni ti o ba mu eleyi ki o mase gbon loju ara re, bi o ba n fe se nkankan ki o mase fun idile re ki won si ma ba gba imoran nigbana ni ohun ti o ba ti da wole yi o dara. Ohun gbogbo ti o ba tin je niyan ni yi o te lowo, ibase obinrin tabi owo tabi ibugbe.

10. BETH: Eleyi yio ri iranlowo lati odo ore re tio wa ni okere. Iranlowo na yio po ti yo fi je pe won ko ni gbagbe ara won lailai. Mase beru lati se ohun tio bere si iranlowo enia wa fun o nibe.

11. CAPH: Sora ki eniti o ti gbekele mase dale, nitoripe eletan enia wa legbe re pelu.

12. AIN: Gbogbo awon eda ti a ri ati eyiti a ko ri lo nyonu si, bi ko ba ti dara fun o to mase foya ohunkohun ti o ba ti dawole rere ni yio yori si.

13. TAH: Idamu owo yio wa fun onibere yi nipa ohun ti o bere si. Bi o ba da nkan na sile tan, bi o ba fe ya owo lodo enia won ko ni ya lowo dipo ki won ya lowo titan ni won yio ma tan je.

14. JODI: Eniti onibere yii gbekele yio se iranlowo fun ti oju ko fi nit i nibi ohun ti o bere si. Bi o ba je pe obirin ni o ni ibeere na ba n fe ki o fe sugbon omo ti yio bi ko ni ju okan tabi meji lo.

15. SCHIN: Laisi ani ani onibere yi ko ni owo lowo ti o ma fi bo bukata re ti o po. Bi o ba n fe lati se ohun ti o bere si, iranlowo awon ore re ni yio fi le sese, nitoripe ipo ti onibere wa loni yi ola awon enia na ni, ati pe gbogbo enia ni yio ma feran onibere yi. Irawo lati se ohun rere jade si onibere yi lasiko yi.

16. HAI: Ki onibere yi mase dija nitoripe gege bi ija dida ni ibere re yi je, onibere papa ti mo eyiti o to lati se o si tun nbere gegebi eni pe ko mo eyiti

o dara lati se, ibere yi dabi enipe ko mo eyiti o dara lati se, ibere yi dabi enipe ki enia bere pe n je o ye ki on jeun ni asiko tie bi ba n paa, tabi ki odo kun ki enia si ma bere pe n je bi o n b a bo si inu odo yi, yio gbe o n lo bi niwon igbati o mop e odo ti kun.

17. RASH: Onibere yi ti bere lati ma ko egbe kan, ki o sora nitoripe ki o to pada lehin awon egbe buburu wonyi yi o ti ko itiju ati egan. Ohunkohun ti o n bere ba n fe lati dawole ko fi sile na nitoripe itiju yio wa nibe.

18. JAJI: Onibere yio ba alatako pade niti ohun ti o bere si, sugbon ki o fi ara da isoro ti o ba wa nibe nikehin ere pupo ni yi o jasi.

19. KOPH: Bi onibere yi ba dawole ohun ti o bere si yi, owo yio da lamu nibe nitori pe koni ri owo se, awon ti o je ni owo won ko ni san ni asiko yi nitorina tubo mu suru.

20. TETH: Bi onibere yi ki ba mu oti tabi emu amupara ki o sora lati ba omuti enia da ise po, bi o n papa ba je omuti ki o din ku tabi fi sile, ki o mase je pe gbogbo egbe re ni yi o ju lo ni ipo ati ola.

21. PSADDI: Onibere yio gbo irohin rere kan laipe ti yio mu inu re dun nipa ohun ti o bere si. Enikan yio ku ninu idile onibere yi won yio si pin ninu ogun ibatan re na fu, rere ni ibeere na yio je.

22. **CHETH**: Ki onibere yi tubo ma hu iwa rere nitoripe iwa rere ti nhu ni yio je ki o ri rere nipa ohun ti o beere kio mase foya lori ohun ti o ba ti dawole rere ni opin re.

23. **PE**: Ki onibere yi yan eyiti o ba fe ninu okan re nitori pe ohun ti o bere si yi ko buru ko si dara ju o wa niwon tun won si.

24. ZAIN: Owo ara eni ni a fi ntun iwa ara eni se ni eleyi ki se pe ota re lo po loju a fowo fa tire ni. Ohun ti o bere si yi boya ni yi o dara . tun iwa tire papa se.

ETO YI DARA FUN IMO AYA

A o ni omi apata, ati omi okun ati omi adagun odo, a o tun mu imope meji peu awe funfun ojo kan, ao o maka awon ese Bibei yi si aposte 2, 2 john 1 to end, ifihan 4, ao mape oruko mimo yi si WAKAIA JAH GOLAMISI (3-3) a o se eto yi ni ojo Friday.

EYI DARA FUN ALALILA

A o ni omi okun ati omi egbon pelu omi iri a o maka awon ese bibeli yi si leemeta Genesis 1 v 1 – 20, a o ma ka si omi na a o mase eyini de, a o omi naa buju.

BACK TO SENDER

Tiwon ba se buruku si wa tabi ka se akiyesi pe a won kan nperi wa ni aburu tabi tafa siwa. A o wa red cande kan, ao wa fi abere aporo kan ko awon oruko mimo yi si ara abea na. EI AJORARA TAFAH JAH, ELI AMUJEMUJESI pelu pslam 109, a o ka si ara abela yen nigba meta arin oganjo oru ojo Tuesday mojumo ojo Wednesday, a o wa gbadura pe gbogbo eda tongbogun ti ogo mi, owu abela ni seku pa abela, ao wa tana si abela yen lori, a o wa ma gbaduara bi a se fe kori fun ota re, a o jeki abela yen jo de idaji, ao wa fi owo mu owu re, tobawa di idaji bi 5am. Ao o so ajoku abela naa soju titi ni espress ni oo ti moto ba n gba dada, lai ti soro si enikankan.

Akiyise: A ki fi ise yii seka ooo, malo si eniti kii se ota re ooo.

ETO ADURA TI ORO EDA BA DARU TO DOJURU TAN

A o ra olive oil kan, ao ka pslam 21, 61 ati 71 (3x) peu adura ki oro wa ki o di ayo kojasi ire, ti a ba jo tan, a o wa lo ri oil yen mo iwaju ita ile ti a n gbe fun ojo meje

Akiyesi: A o bere eto yi ni ojo akoko ti osu ba bere (first day of the month) ti o ba di ojo keje, a o wu ninu ibiti aba rimo, a o mafi pa owo wa mejeji ati oju pelu ori wa.

ETO YI DARA FUN ENI TOFE MA LALA

A o ni omi sinu igo funfun, a o maka psl**am wonyi sinu re nigba ti a ba fe si, psa**lm 29, 19 , 14 ao ma ka nigba meta meta sinu omi a o mape oruko mimo yi ELI SIDIRAJAH(7x) ao mofi omi na we oju wa ki a tosun.

ETO TI GBOGBO ENIYAN FI N NIFE ENIYAN

Turari 999 pack kan, ati igo turari bintu kan, a o gun turari tigitigi kuna dada ori olo, a o wa po papo mo oso eyikeyi,. A o fi turari bintu yen po ose yen papo dada, ao wako sinu ike funfun kan, a o mawe lararo.

ETO IMISI EMI MIMO

Ebu omi sinu cup ofo, efo agbon kan si, eda miss paris oni 100 sinu re, vision oil igokan e tan abela yellow meta yi ka, ki e wa ka awon ese bibeli

yi, psalm 1, 19,84,99,, Isaiah 61, Isaiah 6 v 1-8, Act 2 1-12, 1 sam 10 v 1 - 13, ifihan 10, ifihan 4, a o pe oruko mimo yi ElI WAKUKU(7X) EJIBUARARA (16X)ZOD (21x) a wa ninu awe biribiri ojo kan pere, omi yi a o ti break pelu adura

ETO EBUN IRIRAN

Omi agbon meta, da sinu ike funfun, ki o fi iyo die si, da miss paris sinu re tan imole agbara meje yika, ki e ka Joel 2v 28. Si ni igba meje ki o wa ma fi turari cele ni gbogbo wakati adura. Awe biribiri ojo kan pere, wa pe oruko malaika yi ni dede ago mejia oru ati osan 21 ElI WAKUKU. Wa pe yi ni ajo mesan owuro ati mesan ae ElI MAJIBURAUKA (9x) wa gbadura si dada. O wa fi omi yi boju leyin to ba pari adura ni ago mesan ale.

IKILO: Do not go out after using the water. Iwo ti o je wipe oju ala nikan lo ti nwo inu imisi gbiyanju ati mu die ninu omi adura yi.

ELOITI-SADAI

Oruko yi lagbara pupo, ti eniyan ba pe oruko yi nigba mewa(10) nigba ti ewu kan ba n bo tabi ti ija igboro kan ba sele, tabi ti awon ole ba n dana tabi ti eniyan ba wa ninu ewu jamba kan, eni na yio koja ni irorun, ni agbara olorun, bakana a o ko sinu iwe felefele ki a si fi owu red we, ki ama mu sinu ara wa a tun le lo ni awon ona miran

TAU

Ti a ba ri odo tabi omi konga tiki sun daada, ti a ba ko oruko yi si ara oje funfun nigba aadota odin meta(47) ti aba so sinu omi na,o dajum omi na koni gbe mo yio ma suu si.

TETRAARAMMATOW

Oruko yi lagbara, osi tu wulo lopolopo, Joshua lo oruko yi dada ti a bako oruko yin ni igba ogoji(40) sinu iwe parthment paper tabi iwe felefele, awon igi nla tabi igi soro die die si inu re, a o lo de sinu re, a o lo de sinu re a o di owu funfun, ti eniyan ban lo sibi idagiri kani tabi owa nibi ti walida kan ti se, lufe eni na yio ri abo ti adaju.

TETRAGRAMMATUN-ELOHIM

Enikeni ti o ba pe oruko yi sinu omi nigba ogorun ole okonla(111) ni ago mejila oru, enikeni ti o ba mu ninu omi naa, Olorun yio ma gba won kuro ninu ewu ijamba tabi iparun, bakana ajakale arun, ki yo le de odo won. won koni se aisan kankan ti won ko ba ti torun bo ese rara

VAU

Enikeni ti oba n binu tabi ti ni emi aimo Kankan ni ara, a o ko oruko yi si ara glass tuntun tabi awo ti o fe dada, nigba 100 a o fi oyin gidi ko tabi oje ara igi a o wa fi oni ojo ti o mo so. A ogbe fun inu eni be, inu eni na olorun yio fun ani emi igboya ati igbagbo.

ANAEL

Enikeni ti o ba ko oruko oluwa yin ni igba (111) pelu ink ti o mo dada, a o ko sinu iwe felefele ti o mo dada, a o we ni owu green, a o ri mole fun eniti o ba se ipile ile re a o se ti yio je merin, a o ri sigun ile mererin, eni naa yio ri anu, lati ko ile naa ni kiakia ati wipe abo olorun yo ma wa ninu ile naa, eni naa ki yio ba idana pade, yio se aseyori naa a o ko ise na ni ojo Wednesday

EL-ADONAI- ZABAOTH

Oruko Oluwa yi ni agbara pupo,ti eniyan ba wa ninu igekun tubu, ti a ba ko oruko yi nigba kan soso sori buredi ti a ba gbe, fun eniti o ba wa ninu tubu, ti eniyan basi ri ore ofe je buredi na, o di dandan ki eni naa ri itusile kuro ninu igbekun naa, a si tu le kosi ara glass tabi pako ti o si fi pelu oyin gidi, ki eniti o wa ninu igbekun aisan tabi ti ota ki mu eni na yio ri itusile lagbara olorun, ki a se etoyi ni ojo Monday ni ona (101, ki awa fi omi odo fo sinu abo.

ELOHIM

Oruko oluwa yi ma n sise fun anu ati oju rere, ti eniyan ba npe oruko yi nigba 70 times, ni aro kulukulu ti a sin kaa Ps 4(7x), 65(1x),ki owa ma gbadura ki oto soro si eniyan, eni naa yio ma ni anu ati oju rere ati je atimu ko ni nira fun eni na rara.

ELOHIM-SABAOTH

Oruko yi ni agbara pupopupo, oje okan lara oruko oluwa, isegun ogun, nitori ologun ni oluwa sini oruko re, ti a ba ko oruko yi si ara ounka awon alagbede ba a wa se ti ti eniyan fi oruko yi si owo, o daju ti o ba wa laarin ota,ota ko ni le bori re, ota ibon ko ni le ba eniyen, ti o ba lo si oju ogun eni naa yio ni isegun ni ona gbogbo, eniti o ba wa lowo re, yioni iberu fun awon eniyan, bakana a le ko oruko ni 202 times pelu oyin tabi oje ara igi ti o bam o dada, ki eni naa gbemu, o si se pelu omi inu apata, a o k apata 68(1x), 81(7x) sinu re, bakana a le pe oruko ni fi gbadura a o si nia ape ni ale ni ago mejila orun, a ope nigba(100x) fun ojo meje.

EMMANUEL

Ti a ba pe oruko yi sinu omi fun omode ti o ba ni emi esu, tabi odo ti o ni emi esu, kiakia ni emi esu na yo fi sile, a o pe ni 107 times si ara omo naa,tabi ki a ka sinu omi iwe fun omode naa,a si tun le fi se seal fun omo naa,ki o ma mu si ara,emi esu yo fi omo naa sile.

ADURA TI O N SI OKE NIDI

1) Ka owo re mejeji le ori re, ki o pe oruko Jesu nigba meje pelu itara “oja tan n ferin taa, ti won n fekun san owo re Oluwa ma je kimba won ra. Ni dede agogo kan oru tabi osan.
2) Oruko Jesu ni igba meta ile tis u ti ki mo, Oluwa ma se je o sumi.
3) Gbogbo agbara to n fi aye mi da majemu ibi, Oluwa fi iku gbigbona bee aye won wo, lori ikunle fun odidi ogoji iseju pelu itara.
4) Pe Oruko Jesu ni igba meje, Oluwa gba mi, iji ojo ale ko gbodo ja mi
5) Oluwa, alagbara to lohun fe fi aye han mi, Oluwa fi owo agbara re forum loni. Lori oke ati ninu ijo Olorun
6) Enikeni ti o n mu omi, to n gbero ati se mi ni ibi Oluwa je ki omi aye gbe lo
7) Pe oruko Jesu nigba meta Oluwa ma je ki n fi oposi agba eto mi
8) Abami owo to n ja aye mi ni ogun, e ma gbe danu ni oruko Jesu, e dawo ise yin duro lori aye mi
9) Gbogbo ogun ifikuluku to n ja aye mi logun, ni oruko Jesu e dawo ise yin duro lori aye mi

10) Gbogbo ifowosowopo okunkun lori aye mi ni oruko jesu e maa gbina danu
11) Oruko jesu nigba meje , pelu aawe ojo kan , ogun ogode emi pin oluwa wase je ki o je ipin mi .
12) Oluwa gbami fi owo agbara re ti ilekun mo ogun a sin omo eda de eti iboji . gbigba ni ojo jo Friday .
13) Ajo temi oni ba won ko oluwa maje ki n ba won da.
14) Ogun aisan kogboogun , oluwa ma se je ki o de ba mi .
15) Gbadura yii ni dede agogo kan oru Wednesday aisan osan kan oru okan oluwa ma se je ki o wo inu aye mi.
16) Ni oruko jesu aga ogo mi , oluwa ma se je ki o di eewo fun lati fi joko.
17) Ni oruko jesu eni ti o n fi ibere aye ja mi logun oluwa beere fi iye ojo aye re ja ni ogun orun apadi ,
18) Ojubo agba tan ti n fi ipin mi rere , e ma gbina ni oruko jesu .
19) Abami eja n la to n da omi alafia mi ruu . oluwa ba mi fi iwo gbe loni ni oruko jesu .
20) Oluwa gbami maje n da eru mi danu losan gangan .
21) Oluwa gbami lowo kootu aye,maje kin fi ekun ro ejo.
22) Ni oruko jesu inaomo ko gbodo jo mi .
23) Ni oruko jesu ina aye ko gbodo jo mi .
24) Ni oruko jesu alaanu mi ko gbodo ri idamu .
25) Irin aajo aare maabo , oluwa maje ki kin rin .
26) Oluwa gba mi ma je ki n di eru aruka .
27) Oruko jesu nigba meje iboji ti aya fi di olore mi loju , kia k ina ori pepe ma ka kuro lowolowo ni oruko jesu.
28) Pe oruko jesu nigba meta , eje jesu nigba meta ,oluwa fi ina re bo aso ogun ti aye gbe wo mi .
29) Dingi aye , ti ota fi now ire ayanmo mi ara ode oru ma fo dingi naa loni .
30) Gbogbo olufisu mi , ni oruko jesu e ma bo sina takate olorun loni.
31) Gbogbo ota ti n fi oro mi le oso ati aje lowo , e ma gba idajo iku loni.
32) Mo pa ni ase ni oruko , eya ago ara mi o gbodo fimisile saye lo.

33) Enikeni ti o ba ja ogba tutumi ejo yoo bu san enikeni to ba lohun fe se mi ni ibi , ki o se ara re .
34) Ese mefa ti aye wo sile de omo mi tabi emi , ki won wonu re loni ni oruko jesu.
35) Oro aye ti ota pe sinu aye mi loruko jesu e ma jade ninu aye mi.
36) Awon agba omiran ti o n ba aye mi jakadi , temi ko fi oju ri ni oruko jesu e magba idajo gbigbona lati oke wa .
37) Adahunse tabi alalupayida to fi aworan mi se ise ibi , oluwa bami ja okun emi won loni .
38) Pe oruko jesu to san bi ara , kigbe wipe owo agbana tawon aye naa fun mi loju ala jesu ba mi fi owo naa tawon lore ojiji.
39) Opon aye ti ota fin pon mi loju oluwa da ina sun opon naa ni oruko jesu .
40) Oluwa gbami lowo ajunilo, ere ko ba mo , ere ko sese mo, oluwa mase je ki n ba sa lori omo.
41) Ogun fikan gba kan oluwa mase je ki o je temi.
42) Mase je ki aye o ja omo gba lowo mi .
43) Alaso ekun ti n pin aso ekun ninu osu yi oluwa ma je ko je ipin mi .
44) Yeri awon agba , sokoto awon agba , ma je ki aya fi won mi .
45) Ofafa ti aye fi n fa ire aye mi ni oruko jesu oluwa fi gegun iku loni.
46) Alabojuto ti awon agba yan timi ,lati ma dowo bo ogo aye mi ina orun bo so won di eeru loni.
47) Lori ikunle s iduro pelu rinrin lori iduro , oluwa gba mi ma se je ki takute esu o mu mi ati omo ni oruko jesu.
48) Ni oruko ,ogun asita ibon ko gbo je temi .
49) Ise ewe s egbo lori mi ti ota fi n je mi ni iya , jesu ba mi fi eje re ba je loni ni oruko jesu .
50) Oluwa ra iseda mi pada ninu aginju ti aye ta si loni .
51) Oluwa la ile mi koja loni .
52) Ni oruko jesu aye oo gbodo fi iseda gba paaro.
53) Alagbara jagun jagun omiran ti o n ba aye mi ja ogun emi e ma gba idajo gbigbona iku loni .
54) Ogiri ti awon ota gbero lodi si ire aye mi ema wo lule.
55) Gbogbo eku aye , ti o n ja mi lole ninu emi e ma bo sinu takuta .
56) Oluwa mase jeki omo araye ki o ba ewa ara mi je .

57) Oruko jesu nigba meje ogun amubo oko tabi amubo aye mo dagbere fun yi ninu aye mi.

58) Gbogbo owo ti o n gba ounje omo danu ni enu mi e ma gba idajo gbigbona loni.

59) Apeere aye ti awon alagbara okunkun nko ile adura mi si ,ti adura mi ko fi je ite wogba ni odo olorun mop e ina olorun alaaye sori apeere naa ko jona loni .

60) Oluwa je ki ifarahan mi ko bere si ni fi ipaya ba ota.

61) Yara oju rere ti won ko si fun enikeni ri ninu iran mi o ya silekun oju rere mi sile fun mi.

62) Oruko jesu nigba meta ati eje jesu nigba meta sa n ara pa awon igbimo ko fe mi fun ire igbimo ko fen i foro.

63) Gbogbo igbimo ibi ti an se nitori temi ninu isa –oku ,ninu omi loju ofurufu ,ninu igi , lori apata ati lori ile , jeki ina orun ko jo wo .

64) Afara ti o so ota ile mi ati ode papo mo mi, oluwa fi ara ode orun jafara naa danu .

65) Aje tabi oso ti won bi mi loju e, ti won fa oro mi le lowo ati ise ibi simi , oluwa bami fi ina orun pawon danu loni .

66) Aje tabi oso ti mo nbagbe ile papo to n fi ogun ajogbe ja aye mi ,oluwa name ta won ni ofa iku loni .

67) Asoju awon agba to n mu ejo mi sun ni ikorita aseyori ise rere mi oluwa ba mi daju ogun ko won ni oruko jesu .

68) Gbogbo onidiri okunkun ti o n sise akanse lori irin ogo aye mi ara orun san pawon.

69) Gbogbo agbara ti o pinnu lati fi asale mi pon mi loju e ma ku iku ojiji ni oruko jesu .

70) Gbogbo ijoba ti o joko lori eto mi emi mimo ode orun ,eyin angeli mimo ode orun , ebeere ise lori won loni aga won ki o beere si ye mo won ni idi.

71) Alagbara ika eniyan , ti o n fi ipin mi bun i ihoho oluwa je ki otutu aye ki o pa ika eniyan naa.

72) Ni oruko jesu ki ara ti o dapo mo ina san pa gbogbo eniyan ti o fi aworan mi damu mi ti o fi n se ibi simi.

73) Fi owo gba ile ni eemeta , ni oruko jesu nigba meje ,so wipe iwo ile kini o gba lori oro mi ti ara fi nimi lori re mo pa ni ase ni oruko jesu .

74) Lori ibujade ogo aye mi , oluwa je ki awon ota mi ki won fi ibinuje se ipade ni oni.
75) Ado iku aisan ,ti awon eleye ati oso toju si ago arami , ti ara mi ti ara fin ni ,bibeli wipe aya yoo pa alejo mo won yoo fi iberu sa jade ni ibi okolofin , jade kuro ni ago mi loni .
76) Ile ajoji ti won ta ohun rere aye mi si ni oruko jesu mo re won pada ni loni.
77) Ni oruko jesu , olugbala gba mi lowo ika okunrin ati ika obinrin ti o n loo aye mi mole bi ero ata.
78) Oluwa di won lowo ise loni , gbogbo obinrin obiripo aye ati okunrin abaje lenu sooro soo , ti won fe ta ogo aye mi ni gbanjo ni oja okunkun agbaye .
79) Gbe ese mefa si wa ju ,mo won ese mefa fun yin gbogbo eyin ti iwa laaye yin , n di igbega mi lowo agbara iku , ipooku e ma gbe won mi .
80) Ni oruko jesu iyo mi o gbodo di obu .
81) Gbogbo gbere ti a sin fun mi ni igba aimo , ti o fa ogun ati idamu sinu aye mi loni , mo pa ni ase ni oruko jesu , ki eje jesu beere si ni pa oro re ni ago ara mi loni .
82) Gbogbo epe , afose ,gbetugbetu ati okaraba , ti won sa si iseda mi mo pa ni ase , ki epe ki o pada sori elepe .
83) Oluwa ba mi fi owo agbara nla di gbogbo ko to ti aye n ko ire aye mi si ni ososu ni oruko jesu.
84) Oluwa mo mi wo yara agbara nla re lo , ma je ki ogun epe , asasi ki o ran mi lati oni lo ni oruko jesu .
85) Oluwa gba mi , ma je ki n fi owo ara mi oluwa ma se je ki n fi owo ara mi se iku pa mi.
86) Gbogbo woli ti o n gun ori oke lati se lodi si kadara mi yara oju rere ko ti mo woli naa .
87) Iduro tabi ibere ko si fun eni ti o gbe odo mi , alfa ti a fi oro aye mi le lowo lati kehun tabi di tira mo mi ni tori oro mi , ki alaafia ki o jina si alfa neti lati oni lo.
88) Babalawo ati onisegun ti o gba lati je ise ibi ti ika eniyan ran simi , ki o to bere ise lori mi je ki o ki iku ojiji .
89) Ogboni ati alawopa ti o n ja ewe ati egbon tori temi , mo ran angeli alaianu si lati lupa ki oto di ojo meje.

90) Oluwa le ipa won de iboji oku , gbogbo ebora , iwin , esuku ti a ran si mi lati pa ina ogo aye mi.

91) Oba aye ,ati awon ijoye , ti won n lo igi a mi mo ti won oluwa ro ojo le won lori .

92) Gobgbo eye abami tabi eranko abami ti o ba fi koja lori ile aye mi , kin won ma kigbe oro wo iboji.

93) Oluwa fi owo agbara re gbami lowo oga ise mi ,ti ko fe ki ogo aye mi bu jade.

94) Fi owo otun re gba iku re igba meje , oruko jesu ni igba meje ,gbogbo ounje oju al ati mo je to fa aisan sinu aye mi , e maa jade lago ara mi.

95) Ojo ti awon igbimo okunkun fi da ojo ibi run mi , pe emi ……omo ,..ma sun ekun kikoro oluwa yi ojo ibi naa si ojo ayo mi.

96) Ero ibanisoro ti okunkun nlo ti won fi ngbe oro mi kiri lati oni lo mo pase ko gbodo sise mo lati oni lo.

97) Ase pari asoko awon agba ti won so ko , ti won ni ko gbodo kan ile , nitori temi oluwa ti won ara ina ja lu ile .

98) Alagbara ika eniyan to lo fi mi se ogbede tabi ibepe ti o fe lo be ogede ati ibepe ni epe nitori temi fi iku be won wo

99) Eyin igi igbo , ope igbo ,egbo oro oluwa ,e ko gbodo gba ibody mo ni oruko jesu .

100) Enikeni tabi ohunkohun ti o ba fe lo oruko mi lati ja mi ni ogun , mo pase ni oruko jesu kristi ma wo pa won .

101) Gbogbo oro ti ota ti ba afefe tabi ofurufu so nipa mi to fa ogun sinu aye mi, oluwa fi oro re se itusile , fun mi loni .

102) Gbogbo oro ti ika ba ile so , ti won ba iji so nitori temi , oluwa je ki won da owo ise duro lori mi loni.

103) Ilu tabi ile ti mo ti gberi, to fa ogun ati ijogbon sinu aye mi ,eje jesu ma pa oro re lara mi loni.

